# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. NO. 35. SATURDAY, MARCH 10, 1923. FOURPENCE.



*Editor & Proprietor:—*

ADEOYE DENIGA,

*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.



N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall (Customs Street,)* EKO





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Meji'a tabi jubẹ lọ ninu MASINI n.i.

Awọn Oyinbo yi nṣe oriṣirisi ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati oriṣirisi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

*( Macaulay's Household Dispensary.)*

Anta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni opopo-nla ( *Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ o.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Arun to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Ọ. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbog yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo ( *Certificated Dispenser.*) lowọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO. Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Ka'awa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Aşo abọmọlọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun tọ ni

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe ( *General Post Office* ) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ ( *Telephone* ) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA

Ọgbẹni D. B. OŞUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Şabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aşọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, ( *Satten.*)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbeni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany,) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGEE MI LỌ YI O? ORUN!

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şẹşẹ de fun u pẹlu awọn MAŞINI iranşọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Măse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

### ITIMO 'LE KO K' ẸNIKAN.!

Yara kotopo mẹrin tọtọ ni awọn Alaṣẹ-ọlọpa nṣe sinu ile-ọgba awọn Ọlọpa ni Ita Tinubu nisisiyi, fun titi eni to ba ṣẹ mọ, a ti le awọn Aranṣọ-ọlọpa to ti wa nibiyi ri lọ si "Ilẹtẹ Ile-iku"...Ikoyi.

### ỌMỌ ILE-IWE NRẸHIN BI OGUNNA.

Boya pupọ obi ko mọ pe nwọn nṣe ọmọ wọn leṣe ni nipa aitete le wọn lọ si Ile-iwe nigbati agogo ba lu irufẹ ọmọ to ba pẹ bayi ni awọn Olukọni ma nti ilẹkun mọ si ita; titi di agogo mẹwa tabi di igba ijade ọsan-agogo mejila, lọna yi, a ko le ṣeṣẹ ma sọ ti adanu ti awọn ọmọ bẹ npa, nigbati nwọn ko ba le ba awon ẹgbẹ wọn ti nwọn ti tete de ibẹ ṣiwaju wọn kọ ẹkọ pọ ni *class*. O dọwọ nyin o ẹnyin obi, ka ma ri ọmọ to ma joye awọn alaigbọn wundia marun igbani.

### AGBAKO DI MEJI OKAN.

*Kikọlu* ti awọn kẹkẹ *Motor* nkọlu ara wọn lode npọ nisisiyi tobẹ to fi jẹ pe bi enia ba nlọ sode, adura agba-sinu ni yi ma gba pe ki on ma ba agbako ikọlu awọn kẹkẹ wọnyi pade, ki on to de'le. A mọ awọn Iya to jẹ pe aya wọn ki nbalẹ lọna bayi, titi awọn ọmọ wọn ma fi pada bọ wa si 'le lati Ile-iwe. Ni lọlọyi ni a gbọ pe ọkọ-iyawo ọlẹṣẹ-osun kan ni Ita Oluwọle fi ara gbina epo *petrol* tobẹ to jẹ pe o fin lara pata-pata, ko si ẹniti ko ni sọpe gbogbo nkan-ilaju ti a nlo lode oni lo mu ewu dani. Oṣe! Alufa M. L. Stone, ọrun rere!!!

A ranti ọrọ ijinlẹ kan to sọ ni sa.kan nigbati o nwasu nipa ohun ẹrọ ilaju wọnyi to fi wipe "Ṣifilisaṣọn ki o jẹ ẹ roju" "Ṣifilisaṣọn ki o jẹ ẹ t' ọjọ" eyini ni pe awọn ẹrọ ilaju wọnyi yio jẹ inira fun wa lode aiye: o dabi ẹnipe ọrọ na njalẹ loni. Ọlọrun ma jẹ ka rin nijọ ebi np'ọna !!!

### YE, IKU DORO.!!!

A ba Ile-iwe giga ti Eko ati awọn ẹbi Omidan Toṣọ Layinka ọmọ Ọgbẹni Akidele Dawo'n, Ologbe, kẹdun iku omidan na to ṣẹlẹ lọsẹ yi. ṣiwaju iku rẹ Olukọni awọn ọmọde ni Ile-iwe yi ni ologbe na jẹ. O to ọmọ ọdun mejidin-logun, Iya rẹ si nbẹ sibẹ, Abiamọ ku'rọju.

### OKU ỌLỌMỌ GẸGẸ LA O GBE E EYI 'O LỌMỌ GẸGẸ LAO GBE. A F' EYI 'O LARA!

A ba Ẹni-ọwọ Evan Williams ati awọn ẹbi rẹ kẹdun ọfọ ti o ṣẹ wọn ni ọjọ ọsẹ to kọja nipa iya wọn Priscilla ti ko si, a si gbe e sin ni Ikoyi ni ọjọ *Monday* ti o tẹle. Ọmọ oniku, ẹ ku ọfọ.

### TIRE T' AYỌ, ALUFA APỌN B' EPO-RẸ.

A ba Ẹni-ọwọ J. A. Leigh Oloye M.A. yọ fun lilori, ti a gbọ pe ọrọ rẹ nipa ti rogbodiyan *Church* rẹ, eyi ti a ti sọ ninu Iwe-irohin yi lori ninu Ipade ti awọn Alaṣẹ *Church* na ṣe ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ to kọja ninu Gbangan *Grammar School*. Ọ kutọ, A-fi-'we-ṣe-fuja.

### B' ỌMỌDE DE 'BI ẸRU, ẸRU A BA A

Ihin kan ni lati ilu *Victoria, Kamarun* wa pe iṣẹlẹ kan ṣẹ ni agogo mejila ku iṣẹju mẹdogun ọsan *Thursday* ọjọ kẹdogun oṣu to kọja. A dupẹ pe ko si "kuku" larin awọn ara wa, ati awọn ara ilu na nigbati ewu yi ti rekọja tan.

### GBA-NGBA D' ẸKUN, KEDERE BEWO!

Ọwọ lẹ ọgbẹni to npe ara rẹ ni Zazra ṣugbọn ti oruko rẹ papa nje Arthur Drew Clifton ti o ti ngbowo lẹ lati ọdunmọdun sẹhin wa lọwọ awọn enia wa nibi, ati ni ilu okere miran bi England, to ni on nṣe "awure" fun wọn ti o si nṣa 'wo mọ wọn lara.

Ẹnyin ...awe wa yio ranti pe a sọ nipa ti Ọgbẹni Ọlẹdarun yi sinu Iwe irohin yi ni oṣu diẹ sẹhin.

Nję, Ọgbẹni na "ba onile nle" nipa "wiwo nkan" fun orimayaki Olori-Ọlọpa Inu kan ni *London*, nwọn si ra a mu, o jẹbi pe iṣẹ-abosi ni o fi ngbowo jẹ, a si bu £25 fun ni sisan s' apo Ọba o si san £10. 10. owo irin-ęsẹ.

ABỌ, O!

A ki Sẹkitẹri pataki ti Ijọba *Nigeria* Sir Donald Cameron K.B.E., C.M.G. kabọ lati ile, nibiti o ti gba Isinmi lọ.

Sękitẹri Oloye na ba ọkọ "*Appam*" de lana ni agogo mẹsan-abọ arọ.

AWỌN 'RA WỌN KA ṢAI BA'RA WỌN JA!

A gbọ pe ni ibi Apejẹ pataki kan ti awọn kan ṣe fun Oyinbo ọlọla kan ni koi pẹ yi, awọn agbalagba meji kan nibẹ bẹrẹ si ta ohun ẹbu si ara wọn.

A gbọ pe ọrọ na le gidigidi tobẹ ti nwọn fi tu itọ si ara wọn loju, ọrọ Eleko ti ẹnikan ninu wọn dasilẹ la gbọ pe o mu ija na wa.

IFIHAN OHUN ỌGBIN ATI AWỌN IṢẸ TI A FI ỌWỌ TABI ẸRỌ ṢE TI GBOGBO ILU TI O WA LABẸ IJỌBA GẸSI. (1924)

*Awọn ọrọ ti Olu-Ọla Gomina sọ nipa rẹ ni eyi:—*

Ọlọla Adele Sękitẹri ti Ijọba.

1. Ifihan awọn ohun ọgbin ati awọn oniruru iṣẹ ti a fi ọwọ tabi ẹrọ ṣe ti gbogbo Ilu ti o wa labẹ Ijọba-Gẹsi eyiti nwọn ma ṣe ninu Ọgba-nla kan ti a npe ni Ọdan-gbalasa ti *Wembley* lati oṣu *March* titi de oṣu *June* ni ọdun 1924, yio jẹ eyiti o tobi julọ ti a ko si ṣe irufẹ rẹ ri ni gbogbo awọn Ilu ti o wa labẹ Ijọba Gẹsi. Ipalẹmọ tabi imura ti awọn enia nṣe silẹ fun akoko na ko l'ẹgbẹ, wahala nla ni gbogbo awọn Ilu ti-o-nda-ṣe-itọju-ilu-wọn nṣe lati wa fi iṣẹ ilu wọn han ki gbogbo awọn enia ti o ma wa wo iran le mọ irufẹ ilu ti o mu ohun ribiribi wọnyi wa, ati pẹlu lati fi nkan wọnyi han lọna ti inu awọn alafojuri ma fi dun, ti ẹnu o si ya wọn, ti nwọn o si fi ẹnu ara wọn wipe "Loto, awọn ilu ti o mu irufẹ ohun bayi wa, nwọn ni nkan ribiribi ni ilu wọn," ti nwọn a si ma ronu nipa rẹ titi lai.

2. Emi nwewe lọna kini, mo si ti da-mọran lati yọda Eji-din-logun-le-ọgọrun pọnwọ £35,000 fun inawo ipalẹmọ awọn nkan ti ilẹ *Nigeria* ma mu lọ; mo si tun muta bi fi owo si i bi eyiti mo yọda ko ba to bi jẹ ki ohun ti a nfẹ nibẹ ki o le tẹ wa lọwọ.

3. Ọgagun C. T. Lawrence, ti o mọ nkan nipa gbogbo awọn Ilu ti o wa jakejado ilẹ *Nigeria*, ati awọn enia pataki ninu iṣẹ-oba ati awọn ti o jẹ aṣiwaju ninu ohun gbogbo ati oyinbo ati enia dudu, ni gbogbo ilu ti o wa nilẹ *Nigeria*, gbogbo awọn enia wọnyi ni mo ti pe lati jẹ awọn ti o ma wewe ọna ti a le mu iṣẹ na gba, lati ọjọ kini oṣu *January* 1923, Ọgagun Lawrence yi ni mo si fi aṣẹ gbogbo rẹ le lọwọ nipa iṣẹ ti ifihan ni gbangba ti awọn ohun ọgbin ati awọn oniruru iṣẹ ti gbogbo ilu ti o wa labẹ Ijọba Gẹsi, ani ti ilẹ *Nigeria*. Ninu ipo titun ti mo fun Ọgagun Lawrence, on yio jẹ ọkan ninu awọn Ajẹlẹ agba. Mo ti pinnu lọkan mi lati fun u ni gbogbo iranlọwọ ti o ba nfẹ lati ọdọ mi, mo si fẹ ki gbogbo awọn ọga ti o nṣiṣẹ labẹ Ijọba ki o mọ pe mo ti fi agbara fun Ọgagun Lawrence ohunkohun ti o ba ṣe o di aṣegbe, ọrọkọrọ ti o ba si sọ, o yẹ ki o wọlẹ nipa ifihan awọn ohun ọgbin ati oniruru iṣẹ ti gbogbo ilu ti o wa labẹ Ijọba Gẹsi. O da mi loju pe gbogbo ẹnyin ti o mba mi ṣiṣẹ pọ ninu Iṣẹ-oba, lati ọdọ agbalagba titi de ọdọ ọmọde yio ran Ọgagun Lawrence lọwọ ninu iṣẹ pataki ti o fẹ bẹrẹ lati ṣe mo si tun gbẹkẹle gbogbo awọn ti o jẹ ọga nibi iṣẹ pe nwọn o lo gbogbo agbara wọn gbogbo ipa wọn li oniruru ọna lati ran Ọgagun Lawrence lọwọ, ati pe gbogbo wọn yio si kun u lọwọ ki gbogbo nkan ti *Nigeria* yio mu lọ fihan le jẹ eyiti o yẹ ilu wa ninu eyiti o jẹ anfani fun wa lati ṣiṣẹ ninu rẹ.

4. Mo si tun ni igbẹkẹle bakanna si gbogbo awọn ti ko si ninu Iṣẹ-ọba pe nwọn o ran a lọwọ, ati pe nwọn o si fi tinudidun-tinudidun ba a ṣiṣẹ eyiti a ti pe e si lati ṣe.

5. Mo fẹ sọ nisisiyi nipa ti ohun ti o mu ifihan awọn ohun ọgbin ati gbogbo iṣẹ ban wa ni ilu Oyinbo gẹgẹ bi emi ti nfi oju wo, bẹ na ni mo fẹ ki gbogbo wa ni *Nigeria* fi oju wo o.

6. Ki a ma ṣe fi oju fo anfani ti o ma ba owo ati gbogbo Iṣẹ-ilu wa da bi gbogbo nkan ti *Nigeria* ba mu lọ ba je eyiti o ma gba ẹbun ti o si ma jọ awọn ilu iyoku loju. Gbogbo enia lo mọ pe, owo ti iwọ orun Afrika jẹ eyiti o ṣe pataki, gbogbo awọn Onişowo li o mọ gbogbo iṣoro ti o wa ninu rẹ ati awọn onişowo ti o nfi ẹrọ şiṣẹ ti Gẹsi, ati ti awọn gbogbo ilu oyinbo, ati ti awọn Amẹrika ti awọn onişowo ti a ti darukọ ri mba ṣowo, pe boya ni ifihan nla yi ti a ko ṣe irufẹ rẹ ri, ti a si nmura lati ṣe pẹlu ọwọ ti o roke le mu ero ti awọn enia nro nipa iṣoro kuro lọkan wọn lẹnakọna ati pe boya ni gbogbo wahala ti a nṣe yi le jẹ ki owo ma dara lọ siwaju ati siwaju. Nitorina, li ero temi ka ma ṣe ro mi pe ng o fi ẹnu ṣata awọn ohun-ifihan ti *Nigeria*, ti a ba fi oju dubu wọn nipa owo wa ati iṣẹ-ọwọ wa, eyiti a nṣe ati eyiti o wa lati ṣe, ti ilu wa nla yi ti o nda ṣe itọju ara rẹ, mo ro pe ero ọkan tiwa yio yatọ si eyiti awọn ẹlomiran nro.

*Ko ti pari.*

---

ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Lẹhin awọn meji ti mo darukọ ninu iwe irohin ọsẹ ti o *kọja*, o tun ku awọn ẹlomiran ti nwọn ṣe lala *lati* mu orin ni ohun ilẹ wa jade. Fun ọdun diẹ sẹhin, ninu isin opopo ode nikan ni a nlo awọn orin na, a ko yọda lati ma kọ wọn l'akoko isin ninu ile Ọlọrun; awọn Ijọ enia dudu nigbana pẹlu ka a si aitọ lati ma kọ awọn orin na ninu ile isin. Ọna ara l' Ọlọrun ngba şiṣẹ rẹ l' aiye. Nigbati akoko Oluwa to lati mu ki orin kikọ ni ohun ilẹ wa tan kakiri, Ojiṣẹ Ọlọrun S. A. Oke ti o nşiṣẹ Alufa ni Ijọ *Zion Congregational* fi iṣẹ Ijọ na silẹ, o si ko agbo kekere kan jọ ti o sọ ni *Aethopia Church* (Ijọ gbogbo enia dudu ni agbaiye,) nitoripe ifẹ inu rẹ nigbana ni lati da Ijọ Ọlọrun kan silẹ ti a o ma sin ni aṣa ati pẹlu orin ni ohun ilẹ wa. Nigbati Ijọ na bẹrẹ, a ri i wipe Batakoto, Konkolo ati Duru ni o nlo fun kikọ awọn aṣayan orin ti o ṣe. Ni alẹ ọjọjọ-isimi, ile isin rẹ nkun fun ero-ya-wa-woran, eyiti o fi han pe awọn orin ti nwọn nkọ pẹlu Batakoto, Konkolo ati Duru li o nfa ọgọrọ enia lọ si ibẹ lati jọsin fun Oluwa. O yẹ ka f' ọpẹ fun Ọlọrun nitori iru ẹmi ti o fi sinu Ojiṣẹ Ọlọrun na lati mu iru ẹtọ isin bayi jade. Bi o tilẹ jẹ pe a ko gburo Ojiṣẹ Ọlọrun na pẹlu Ijọ rẹ ni igboro Eko l'oni mọ, nitori a gbọ ni sa kan wipe Alufa na ati Ijọ rẹ ti dagbere fun Ekó, sibẹsibẹ ilana ti o fi silẹ yio wa ni iranti rẹ titi.

Kete ti Ijọ *Aethopia* fi Eko silẹ ni o dabi ẹnipe Ijọ *Brotherhood* gba aṣa lati ma lọ Batakoto, Konkolo ati Duru ni akoko isin, awọn ti o nlọ sin nibẹ le jẹri wipe lati igbana ẹsẹ ko gbeji ni isin alẹ ọjọjọ-isimi jẹ, o si mu iṣiri pupọ ba Alabojuto Ijọ na.

OYENẸYẸ.

---

THANKS FOR SYMPATHY.

The undersigned hereby returns his sincere thanks to the Christ Church Faji School Staff, other friends and neighbours who have sympathised with him on the death of his personal friend Mr. E. J. Adekoya an Assistant Headmaster in the School, which sad occurrence took place on the 26th *ultimo*.

JAMES O. AIYE-OLA.

---

## *Correspondence.*

To the Editor "Eko Akete"

Dear Sir,

In reply to an article in your valuable Journal Vol. 1. No. 28 of Saturday the 20th, January last under the Head of "Correspondence" conveying congratulation to Mr. E. J. Ade. Johnson, Senior Clerk in the employ of Barrister E. J. Alex. Taylor, in attaining a Second Class Certificate in Pitman's Shorthand which was said reached him by T. M. S.V. "Adda," I am to inform the interested public that the certificate above referred to reads "M. I. P. S." and that the Second Class Certificate was won on or about the 1st February, 1922.

Mr. Johnson is the Second holder of this M. I. P. S. Certificate in Nigeria.

With every wish for his further success,

Yours sincerely,

ADEOLA ADU.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, March 10, 1923.

### ALAYỌNUSỌ, TIRẸ TI JẸ?

Gẹgẹbi a ti ka Ọgbẹni Abdur Rahim Nayyar Oni-isin *Ahmadia* si, larin wa nibi ki o to lọ, ti a si ngbe e gẹ̀gẹ̀ ti a ṣebi enia ni, o jẹ ohun ti o ya ni lẹnu pupọ lati ri pe nigbati o de ilu Oyinbo ti o nrohin ohun ti o ti ri ni gbogbo ibi ti o lọ, ni Ashanti, ni ilu Aganyin, ati ni *Nigeria* tiwa, fun Oniwe-irohin *West Africa* ti ọjọ 27 oṣu *January* to kọja, ọrọ ti o ṣe e sọ, ati eyiti ko ṣe e sọ lo nsọ bọ̀rọ̀ bi afi-ata-sẹnu. Ẹniti o npe ara rẹ ni Ojiṣẹ-Ọlọrun lọna ti *Ahmadia* si nmọmọ sọ ọrọ ti oju rẹ ko to tabi ti ko mọ idi rẹ: o sọ nipa ti ija Imale o fọ pọ mọ ọrọ ti Eleko, o dori mejeji kodo: ọtọ lo fi ọrọ ṣata Eleko; bayi ni ọkunrin yi fi ṣupa-ṣubi ninu Iwe-irohin na: Enyin Musulumi ọmọ-ẹhin rẹ nibi, a bere, bayi ni Alukurani sọ pe ki e ma a ṣe bi? Ọpọlọpọ ninu awọn ọrẹ to ka iwe na lo bere lọwọ wa pe "pa-nti-wà?" gẹgẹbi ede Abẹyọ; ṣugbọn tani a ba ri bawi? Akukọ lo fi ogbe ori rẹ fun kọlọkọlọ yẹwo: iba ṣepe irẹpọ ati iṣọkan wa larin wa fun rere ilu wa, a ha le ri Alaikọla-ete kan gẹgẹbi ọkunrin yi ti yio gboju-gbaiya lati sọ ọrọ-aitọ si ni ni ilu okere, lẹhin igbati a ti gba a tọwọ-tẹsẹ nibi tan?

Nipa nkan yi, o yẹ ki Ọgbẹni na mọ pe irufẹ ọrọ yi ko le ṣe ko ma jẹ idina fun u nijọmiran ti o ba tun ni on mbọ wa sibi, eyini nipe ko ni ṣai jere ọrọ alẽbu to sọ na.

A wi tan o nyọ̀mbo Gomina Agba wa, Sir Hugh Clifford, pe ẹni-to-mọ "sẹria" to si mọ agbeka-nkan lojẹ, kini ibati tun wi? O gbọdọ sọ omiran ki tẹtẹ ma jẹ ẹ? Ọrọ ọkunrin Nayyar si Gomina Agba dabi ti Ọba Idãsaba ti awọn ẹmẹwa rẹ nki pe "Ọlọrun o s'ẹmi rẹ," Ọba na dahun pe "Tulasi!" iyẹn nipe bi nwọn fẹ bi nwọn kọ nwọn ni lati ma ki on bẹ.

A ro pe awọn ọrẹ wa to wa nihin ti nwọn jẹ Oni-isin kanna pẹlu ọkunrin yi yio ri i gbangba pe Ọga wọn na lọ "fi'ru fọn'na" ohun ti ko mọ'di, ati nipa bayi, Ọgbẹni na sọ ara rẹ di palanta ati ẹni-kekere nitori oye "Fatolu" to fi ara rẹ jẹ yi.

Ara-la-mọ̀, a ko mọ'nu.

---

### HERR BRECKWOLDT.

Herr Breckwoldt of whom we wrote in our last issue, was A General Agent to the German shipping Company, Woermann Linie and Woermann & Co., in Cameroon before the War.

Our visitor in question left on the "Wahehe" on the 2nd instant—*bon voyage*.

---

### POPULAR LECTURE.

*Blyden, The African Educationist.*

This Lecture by Prof. Deniga, is now on sale at the C.M.S. Bookshoop, Lagos at 6d each. "The Taste of the Pudding is in the Eating." *Verb. sap.*

---


### "O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to ẹba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta oriṣiriṣi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ oja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan aro, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

### IYA AFIN SABINA BỌLAJOKO.

Ti No. 39. Ita Matinin jẹ ẹniti o gbaṣẹ ati ma ta oriṣiriṣi ỌTI o si nta awọn nkan Ipanu ni Ṣabu rẹ yi.

Ẹ lọ ke si i, Wàrà-ṣeṣa ni ọja rẹ, owo wọn si mọ-ni-wọn ti makunnu.

# SINGER! SINGER!! SINGER!!!




Kinla! Tiwa ki nṣe a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti nṣ'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbu larin oriṣiriṣi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ "SINGER" kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu 'Ẹlẹha jade ọsan' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

TI ẸDINWO NLANLA TI A ṢE

ninu owo ẸRỌ IRANṢỌ wa ati IRIN-IṢẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANṢỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu iṣẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri oriṣiriṣi irin iṣẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tunṣe nigbakugba lai gba okan gbogbo ẹrọ iranṣọ 'SINGER ibaṣepe a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Broad Street l'eko nibiti 'Ẹrọ Oyibiri' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.

P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*

---

# *ILE EGBOGI TITUN.*

Fun irọrun ati anfani gbogbo awọn ti ngbe Olowogbowo, Ita Balogun, Oke-arin Ọfin, Idumata titi lọ de Victoria Road, a ṣi Ṣọbu egbogi titun kan ni Ita Balogun.

*No. 69, Balogun Street,*

Ṣọbu yi jẹ ẹka Ṣọbu nla ti Filipi ni Ajẹlẹ ati Ita Faji—

*Phillips Medicine Store.*

Egbogi ojulowo pọ nibẹ. Ma fi ọpọ silẹ nitosi lọ ra ọwọn ni ọna jijin.

## Zazra and Ali Obed Khan.

### Thrived on Telling Fortunes.

There seems to be, in the greater part of the human family, something inherent which prompts them to delve into that which is hidden—a desire to know what is to happen to them in the future.

And it follows that there are always those ready to tell them—for a price. Striking confirmation of this was forthcoming in a police prosecution, where it was stated that the person proceeded against had so big a business that he employed five typists.

He was one *Zazra*, Mystic of the Hindoo School of Prediction. This romantic name was the trade name of Arthur Drew Clifton, of Alexander-road, Hampstead, and he was fined £25, with £10 10s. costs, for professing to tell fortunes.

He was trapped by a Scotland Yard detective-inspector who wrote to Zazra in the name of Ali Obed Khan. This is the letter :—

One of my great friends at Lagos has given me your name and says you know all about the wonderful powers of astrology and predicting what is going to happen.

I wish to learn how to know what has not yet happened.

In reply to his letter, the inspector received a pamphlet headed : "Let me read the sands of time for you," together with a number of advertisements for :—

Mysterous bamboo sticks, 10s. each.

Indian fakir crystals for developing the faculty of clairvoyance, 10s. to 25s.

Talismans and charms for success in love.

The book of black arts.

Ways to fortune.

Chi-chi, the daily fortune-teller.

The title of another book was given as "How Not to Grow Old."

"True and real talismanic jewels" were offered for sale at £5, £2, and 10s.

There were also flower and bead necklaces. "Apparently," said Mr. Muskett, "of the same character that are now being found at the tomb of Tutankhamen on the banks of the Nile."

The inspector forwarded 15s. for "A Sketch Delineation of the future," and received a packet of 12 or 13 closely-typed pages which Mr. Muskett described as "a farrago of nonsense from beginning to end."

Parts of it read :—

I find from my observations that a full and varied career is before you.

Your chances of advancing to a higher plane are indeed good.

Your increase of income and fortune should be rather rapid and to a certain extent unexpected.

Had you married up to the present time ("I have an idea that the inspector is very happily married already," interposed Mr. Muskett,) you would have taken a step in the wrong direction.

Then followed five or six pages of what was called a reading of the planets. Ali Obed Khan was advised to invest in a "terrestrial horoscope" (price quoted.

"One page," said Mr. Muskett, "is what, in my ignorance I should probably call a horoscope." It stated :—

Saturday is your eventful day.

Thursday is your fortunate day.

You should burn incense on Saturday for all things that are very serious.

Your charm should be worn in the form to pendants or amulets.

**FIVE TYPISTS.**

Mr. Muskett said there was no doubt Clifton was making a very considerable profit out of his calling. In one of the rooms at his offices were no fewer than five girl typists.

A great mass of correspondence relating to astrology and fortune telling was taken possession of, along with many letters from persons all over the world and a number of articles such as Clifton advertised scarabs and Egyptian articles of jewellery.

There were five or six typewriters, a duplicating machine, and a cards index.

Clifton was said formerly to have carried on his business, in New Bond-street, under the title of "Zazra the Chief Mystic."

He used different names when writing to different countries.

Inspector Draper said the man conducted his correspondence with natives in West Africa, Lagos, and Nigeria. Protests had been made to Scotland Yard by the Nigerian authorities.

Ninety-five per cent. of the business, however, was not done through the post.

*Reynolds's News-paper.*
*4/2/23.*

### FIRST ENGLISH WOMAN BARRISTER.

Miss Ivy Williams, B.C.L., M.A., LL.D., called to the Bar of the Inner Temple in May, 1922, has the distinction of being the first woman barrister in England— *Daily Mail Year Book for 1923; Page 32.*

### FIRST INDIAN WOMAN BARRISTER.

Friday was the third Call Day at the Inns of Court at which women have been called, and it will be made notable by the admission of an Indian woman Miss Mithan Ardeshir Tata, B.A., M.Sc., Miss Tata, in addition to being the first Indian woman to qualify, shares with Miss Mercy Ashworth the distinction of being one of the first two women to be called by Lincoln's Inn.— *The Times Weekly Edition (London) 1/2/23.*

### FIRST NIGERIAN WOMAN BARRISTER.

When is this likely to be?

[ED—E. A.]

## WANTED.

Young lady required, well educated Speaking fluently Yoruba and English to teach Yoruba about six hours a week to suit pupils convenience. Good pay for right person. Apply at 58, Palm Church Street, not later than the 15th of March, 1923, between the hours of 9 a.m. to 10 a.m. daily.

Lagos, 20th February, 1923.



## ILE OWO-ỌJỌ RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kõtu, l' Eko.



## WANTED.

Reliable Agents required for sale of English Ready-made COFFINS, at Lagos Abẹokuta, Ibadan and Jẹbu-Ode.

For Terms and Conditions,

Apply to A. BANK. ANTHONY,

137, Tokunbọ Street, Lagos.



## A TOTO, O!

A nfẹ Enia "GIRIKI" ti yio ṣe oju Ọgbẹni A. BANK ANTHONY ni Eko, Abẹokuta, Ibadan, tabi Ijẹbu-Ode, lati ma a ta awọn POSI-meremere, ti o ti ilu Ọba wa fun Ọgbẹni Oniṣowo na.

Ẹniti o ba nfẹ, ki o kọwe si Ọgbẹni na. ni adugbo rẹ 137, Ita Tokunbọ l'Eko.


## IGBẸ L' OWO WÀ.

EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọ̀wọ̀ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)

Jurgens Colonial,

Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)

MacIver, African Products,

Association, John Holt, Miller Bros.

Paterson Zochonis,

£12 15 de £13 10 fun *ton* kan

EPO.

£20 10 de £21 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

Lati £24 de £25 10 fun *ton* kan bakanna ati Agege £27 0 0.


## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn kò si kọ̀ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY.*

c/o Anfani Motors

The Marina Lagos.

## *Preachers for To-morrow.*

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Aro,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | Mr. C. W. Wakeman |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6 a.m. | ...St. David's (Jordan) | Rev J A Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. J. C. Cole |
| 7 p.m. | | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. C. B. Williams |
| 7 p.m. | | Bro. C. W. Faulkner-Shaw |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | Rev. J. A. Angus |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. D. O. Mould |
| 7 p.m. | | Rev. D. A. Beckley |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. J. A. Laleyẹ |
| 7 p.m. | | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A Akiọla |
| 4 p.m. | | Bro. J. B. Coker |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Amosu |
| 4.30 p.m. | | Rev. I. O. Oyekunle |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. J. F. Oṣodi |
| 4 p.m. | | Bro. Joseph Adewuyi |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. J. Tubi |
| 6.30 p.m. | Rev. A. A. Paddicombe |

**BROTHERHOOD**

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. Fagbemi Faṣeyi |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbo

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon
Rev. H. A. Lewis

---


## SIMENTI NYAJU!!!

Ọgbẹni Mumuni Ainde ti No. 27, Ita Massey L' Eko ni ejulowo *BIRIKI* fun tita fun ẹnikẹni owo wọn si rọju.

Ẹnikẹni to ba nfẹ ba Ọgbẹni na ra awọn *BIRIKI* yi le lọ ke si i ni adugbo rẹ.

Ki a ri nyin o, Ẹnikeji, Ijafara lewu.

---

## W' Ọ BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WÀ!!!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON, ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu ALAJI MASU ni Ita Agarawu ni owo ọpọku-ọyọku.

---

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti
Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,
Oniṣowo ara Jamani ni
Ita 7, Labinjọ, leti Ita William
lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.
Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafa ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

**Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.**

Ile Egbogi ti a npe ni Işę Olodumare ti o wa ni ... Olove Aromirę ni Obun Eko, kun fun orişirişi awon Egbogi wonyi ti o şęşę de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọşe rę, Egbogi Işaka, ...ojędi. Ela omode, Iba, Ipa orere omode, Egbogi Eda ati Aran Kinişa, Egbogi Inu riru ..., ati fun okunrin pelu, egbogi ki ara okun... le giri (ko ma ye e) ati orişirişi awon eyiti a ko le daruko tan.

Sare lo sibę, ki olora tirę, ọpọkuọyọku ni, bi o fę lori, oma dowo rę o.

"Arun ma jogun, ndagba si ęlęda rę.".

Joshua O. Ade: Craig,
*Alabojuto.*

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lodo Aşoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.
Ogbeni Vidal R. Cole.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you. also unsurpassed remedy for female Neuiasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6 These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store
P.O.Box 201; 109

Vidal. R. Cole
Broad Street Lagos

---

Ogbeni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

...wa iwosi oniruru onję-panu (*Provisions*) ...ni tita: Şęręke şin ni awon Itan-Ęlęde (*Hams*) ti o ni: Oti *Wine* ati awon Oti miran to ni nda ni l' orun:

Ę tete lora ti nyin nibe; awon Ile-oja rę miran tun mbe ni 63. Odunlami Street ati 2, Onikepo Street Ita Faji l'Eko
Ohun a ję lo mba ni lo.

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ę ba fę lo si odo awon ti o polowo oja sinu Iwe-irohin yi, ę jare ę so pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ę ti ri ipolowo oja na ka.

---

**First Class Dressmaking!!!**

Mrs. Abraham Ashake trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

**PAGIDARI!**

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wosi ohun elo, fun Omoge ati Omode-m'eso ti o si nta ni ita oloko o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile oja na, ti a nşe Gbajamo fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi toro.

Egbogi orişi-rişi iwosan oniruru aisan, Ipara olo-orun, ati agborun Jigin-oju, ati nkan mere-mere po to wobu nibę.

Ikan-o-jokan irin işę ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibę ni opoku-yoku.

Onifu-nru wosiwosi ti a ko le ka tan po nibę bere ohun-ko-hun ti o ba nfę yio pese rę fun o.

O ngbero laipę, lati şi ile Ero Idan Awoşeju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Idumagbo.

Şoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibę
Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159* *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, EKO.

---

29, Oripasan Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning, Changing of Plain Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning, or white washing of wall to any kind as Distemper colour etc., Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Vanish and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogall,**
*General Manager.*

---

## Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o si "Sa Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọg J. L. Williams Oloj. e, ati si 34, Ita Ọbadina Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna Isẹ

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m    2 p.m de 8 p.m
Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m
Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lo bẹwo,
Ogun rẹ jire.

---

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:-
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.